KITH & KIN INTERNATIONAL COLLEGE 7/11 Kaoli Olusanya Street, Owode Ibeshe, Ikorodu, Lagos State.

FIRST TERM EXAMINATION 2025/2026 ACADEMIC SESSION

| | | | | | |
|---|---|---|---|---|---|
| NAME | | | | | |
| SUBJECT | YORUBA LANGUAGE | CLASS | SS 3 | DURATION | 2 HOURS |

**IPIN KIN-IN-NI**

**Ka ayoka isale yii ki o si dahun ibeere ti o tele won.**

**AKAYE**

Oloye Akande ni oludasile ile-ise igbe eran pamo si fun tita, ti awon oloyinbo n pe ni kooruumu ti ilu Akoyoyo. O je gbaju-gbaja ati ilu mooka eniyan, o fere e ma sii eni ti ko mo oga yii ni gbogbo ilu naa. O ni iwa omoluwabi, o maa n se aanu fun eniyan, ogooro eniyan nio gba si ile-ise re, ti o si n san owo osu to joju fun, lati mu ise ati osi kuro ni ona won, nitori owo to dile ni esun be nise.

Lara anfaani yii ni ogbeni Niyi ti o je manija ile-ise naa ba wole, awon bii Tunrayo, Moji,Segun, Taofiki, Arowosafe je die lara awon osise nigba ti Rasaki je olode.

Ni ojo kan, bi Tunrayo se pari ise oojo re, o wo inu yara yinyin ti won ko eran pamo si lati se ayewo oja ti won sese ko wa fun won. Lojiji ni ilekun yara naa pade mo on, ko si lejade mo,o pariwo, ko si eni ti o gbo,gbogbo osise ile-ise naa ti lo si ile won, ko si oluranlowo Kankan fun-un. O ta gbogbo ogbon lati si ilekun sugbon pabo lo ja si.

Leyin wakati marun-un ti o ti wa ninu yara yinyin yii, tie mi re ti fere e pin, sadede ni Rasaki olode won si ilekun ti o si doola emi re. Obinrin yii wa bii leere pe bawo ni o se mo wi pe oun wa nibe nigba ti kii se ara ise re ni lati maa se ayewo si yara yinyin. Ogbeni Rasaki wa da a lohun pe lati bi ogbon odun o le marun-un ti oun ti wa ni ile ise yii, Tunrayo je okan lara awon osise ti o maa n se aponle oun, yoo ki oun ni aaro ti o ba wose ati ni irole ti o ba n lo ile, sugbon lonii, oun woye pe aaro nikan ni o ki oun ko ti l ki oun pe o dabo, eleyii ti ko si sele ri. Eleyii lo mu ki oun dide lati se ayewo ayika ile-ise kaakiri pe oun ko tii gba ikini irole. Tunrayo wa dupe lowo re fun lilo ti Olorun lo o lati doola emi ohun.

1. Kin ni o se okunfa aanu ti Tunrayo ri lati odo ogbeni Rasaki?

    A. Ariwo ti o maa n pa ni igba gbogbo

    B. Kiki to maa n ki Rasaki

    C. Lilo ipo re ni ona to dara gba

    D. Owo ti o maa n fun Rasaki

2. Ta ni Olorun lo lati doola emi Tunrayo?

    A. Arowosafe

B. Niyi

C. Segun

D. Rasaki

3. Iru eniyan wo ni a le so pe Tunrayo je

A.Alaigboran

B. Omoluwabi

C. Onigberaga

D. Onisekuse

4. Ki ni ohun to sele si Tunrayo gege bi alayoka ti menuba?

A. Awon ajinigbe gbe e salo

B. llekun pade mo-on ni yara yinyin

C. O gbagbe sun lo

D. Kokoro oko re sonu

5. Ewo ni kii se abuda Oloye Akande?

A. Alaaanu

B. Oluranlowo

C. Onijangbon

D. Onirele

**ETO IRO**

6. Toka si eyi ti kii se oro ayalo ninu awon wonyi

A. Alubosa

B.Goolu

C.Ibusun

D.Osibitu

7. Iro akunyun ni awon wonyi ayafi

A.b

B.d

C.i

D.P

8. Afipe akanmole ni

A.Aarin ahon

B.Eyin ahon

C.Ete isale

D.Ete oke

9. Ete se roboto nigba ti a pe

A.|i|

B.|o

C.|ã|

D.|ɛ

10. Iru apeere oro ayalo wo ni 'Pita'

A.Afetiya

B.Afenuya

C.Afojuya

D.Afinuya

11. Eemi ti a n lo lati gbe iro ifo jade ninu ede Yoruba maa n wa lati inu

A.edo foro.

B.edo.

C.tan-an-na.

D.Enu.

**AAYAN OGBUFO**

**Tumo awon ibeere yii si ede Yoruba**

12. 'Ayo and Sade are always fighting'tumo si Ayo ati Sade

A. fe lati maa ja daadaa.

B. feran ija nigba gbogbo.

C. maa n ja ni gbogbo igba.

D. ti maa n ja daadaa.

13.You are chasing the shadow tumo si.

A.O maa n le ojinji.

B.O mu un ni amubo.

C. O mule mofo.

D.O n le ojiji lasan.

14. Adegoke is the backbone of his family Adegoke ni

A.aremo ile re.

B.aribanuje ebi re.

C.igi leyin ogba ebi re.

D.ole ile won.

15.Health is wealth tumo si

A.ailowo lowo ko dara.

B.ilera loogun oro.

C.olowo laye mo.

D.olowo lo laye.

16.'She is a kind-hearted woman' tumo si obinrin naa

A.gbajumo.

B.je alafe eniyan.

C.je oninu rere.

D.lawo gan-an.

**GIRAMA**

17. 'Dide' je gbolohun

A.ase

B. alalye

C. abode

D.Onibo

18.Omo radarada ni omo naa 'radarada' je oro

A.apejuwe

B.aponle

C.asopo

D.atokun

19. Sola mo nipa ile kiko,ebe kiko ati oko riro. Ewo ni oro asopo ninu gbolohun yii?

A.Ati

B.Oko

C. Riro

D.Sola

20. Folasade wa ni ile. 'ni' je oro

A.apejuwe

B.aponle

C.asopo

D.atokun

21. Ode sun eran ya je ninu igbo. 'SUN ati JE' je apeere oro ise

A.alawe

B.elela

C.asoluwadabo

D.asapejuwe

22. 'Ile ti a fi ito mo, iri ni yoo wo'. Ise kin ni gbolohun ti a fala si se ninu gbolohun yii?

A.Atokun

B.Aponle

C.Atokun

D.Oro ise

23. Olu ti o gbe omo aja ta "gbe ati ta"je apeere oro ise

A.Alawe

B.Aseroyin

C.Asapejuwe

D.Elela

24. Ile ti a ti wa. "ti a ti wa"je______ ninu gbolohun yii.

A.atokun

B.aponle

C.oro ise

D.asapejuwe

25. 'Olu n se kirakita nitori atila' Ewo ni gbolohun afarahe ninu gbolohun yii

A.kirakita

B.n se kirakita

C.nitori atila

D.Olu n se kirakita

26. Ile yii ni mo fe ko 'yii' je eyan

A.Ajoruko

B.Apejuwe

C.Asafihan

D.Asaponle

27. 'Ade fa iwe ya', oro ise inu gbolohun yii je

A.alaigbabo.

B.asoluwadabo.

C.eleyo oro ise.

D.elela.

28. 'Mo ra aso funfun meji'. Eyan inu gbolohun yii ni

A.aso funfun.

B.funfun.

C.mo ra.

D.ra aso.

29. 'Awon omo naa n lo fun idije ere boolu ni Oke Oya'. 'Awon' je oro

A. aropo afarajoruko.

B.aropo oruko.

C.atokun.

D.ise.

30. 'Kanga naa kun fofo fun omi'. 'fofo'je oro

A.aponle.

B.apejuwe.

C.atokun.

D.ise.

E.

**ONA ISOWOLO EDE**

31. Pari owe yii: Ogede dudu o yabusan,omo buruku o_______

A.se ran nise.

B.se mu lo soko.

C.ya lupa.

D.ya janduku.

32.Ona isowolo ede wo lo wa ninu 'Elede ni Tolani'?

A.Afiwe

B.Afiwe taara

C.Eebu

D.Ifohunpeniyan

33.Tisa gba omo leti,eti re si ya.
Ona ede wo ni o suyo ninu ayalo yii?

A.Afiwe

B.Asorege

C.Aponle

D.Iforosere

34.'Ta teru nipaa' tumo si

A.fi ipa gba teru

B.fi ipa ta teru

C.fo

D.ku

35. 'ljoba yoo yegi fun awon adigunjale naa.' "Yegi fun" tumo si

A.gba won laaye lati gun igi.

B.pa won.

C.gbe won gun igi.

D.ko igi fun won.

**ASA ATI ISE**

36. Gbogbo awon ounje wonyi ni a le ri lara ewa AYAFI

A.Aadun

B.Akara

C.Ekuru

D.Gbegiri

37.Eewo pe omode ko gbodo to si aarin ona je eewo

A.imototo

B.ibawi/iderubani

C.idile

D.ikilo

38. Omobirin ti o je akobi ni Yoruba n pe ni

A.ifanu

B.beere

C.daodu

D.mogaji

39.Ninu asa isomoloruko ni aye atijo,ojo_______ni Yoruba maa n se isomoloruko omokunrin

A.kesan-an

B.kejo

C.keje

D.kefa

40. Ninu asa igbeyawo ni ile Yoruba,igbese akoko ni

A.Idana

B.ljohen

C.Itoro

D.Ifojusode

41. Rara gege bi okan lara awon ewi alohun Yoruba wopo ni

A.Oyo

B.Ekiti

C.ljebu

D.llorin

42. Awon onise wo ni a maa n ki bayii ni ile Yoruba? Aredu o

A.Alaro

B.Agbe

C.Alagbede

D.Akope

43.Ewo ni ko si lara irinse ifa ninu awon wonyi?

A.Omo owu

B.opon

C.Ikin

D.Opele

44.Ewo ninu awon orisa wonyi ni o feran epo pupa ju?l

A.Sanponna

B.Esu

C.Obatala

D.Ifa

45. Ona oge sise ni Yoruba ni aye atijo ni wonyi AYAFI

A.ara finfin

B.ila kiko

C.ahon lilu

D.tiroo-lile

46.Olugbodi ni

A. omo ti a bi si ile iwe.

B.omo ti o ni ika owo tabi ika ese mefa.

C.omo ti o wa ninu apo nigba ti a bii.

D. omo ti o gbe ibi korun waye.

47.Oruko amutorunwa ni awon wonyi AYAFI

A.Adigun

B.Ajayi

C.Aina

D.lge

48.Oruko idile ni awon wonti AYAFI

A.Ojewole

B.Adesina

C.Ayantola

D.Ayowole

49. Iru idajo wo ni Lafogido da fun awon ebora Ugbo ti owo te ni lle-lfe? Ki won

A.dana sun won.

B.fi won rubo

C.le won niluu.

D.so won deru.

50. Oja tuntun miiran ti a da silefun Moremi ati awon elegbe re ni a n pe ni oja____ni adugbo okerewe.

A.akesan

B.itaakogun

C.oke esinminrin

D.ita yemoo

**IPIN KEJI**

**Dahun ibeere merin pere ni ipin yii.**

1.Ko apeere oro ise elela marun-un, ki o si lo awon oro naa ninu gbolohun. (10 marks)

2.(a)Kin ni eewo?

(b) Daruko isori eewo meta lara awon eewo ile Yoruba, ki o si fi apeere eewo kookan gbe orisii eewo ti o daruko nidii.

(c) So anfaani meji ti o wa ninu eewo Yoruba. (10 marks)

3.(a) Ki ni aranmo?

(b). Se alaye lori okookan awon wonyi pelu apeere meji-meji.

(i) Aranmo Iwaju
(ii) Aranmo Eyin (10 marks)

4. Salaye awon isori oro-ise wonyi pelu apeere kookan.

(i) Oro-ise agbabo

(ii) Oro-ise alaigbabo

(iii) Oro-ise elela

(iv) Oro ise odidi gbolohun

(v) Oro-ise alakanpo (10 marks)

5. (a) Kin ni gbolohun?

(b) Daruko orisi gbolohun merin pelu apeere kookan. (10 marks)

6. Ko oruko amutorunwa mewaa ki o si so itumo won. (10 marks)